# AFUNRUGBIN ATI IRUGBIN
## Matteu 13:1-23
### ẸKỌ 75 FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "Yio si dabi igi ti a gbìn si eti ipa odò, ti nso eso rẹ̀ jade li akokò rẹ̀; ewe rẹ̀ kì yio si rẹ̀; ati ohunkohun ti o ṣe ni yio ma ṣe dede" (Orin Dafidi 1:3).**

**I Afunrugbin, Irugbin ati Ilẹ**

1. O wọ ọkọ ki oju Rẹ̀ ba le ka ijọ eniyan, Matteu 13:1, 2
2. Afunrugbin – Jesu Oluwa, Oun ni Oniwaasu Ọrọ naa, Matteu 13:3; Marku 4:14
3. Irugbin -- Ọrọ Ọlọrun ti o yè ti o si wà titi, Matteu 13:4; Luku 8:11; 1 Peteru 1:23
4. Ilẹ -- awọn eniyan ti a n waasu Ọrọ naa fun, Matteu 13:9

**II Ilẹ Oriṣi Mẹrin**

5. Irugbin ti ẹba ọna -- awọn olugbọ alaibikita, Matteu 13:4; 13:19; Luku 8:12
6. Irugbin ti ori apata -- awọn olugbọ́ alaileduro pẹ́, Matteu 13:5, 6, 20, 21
7. Irugbin ti aarin ẹgun -- awọn olugbọ ti o kun fun aniyan ayé yii, Matteu 13:7, 22; Marku 4:18, 19; Luku 10:40, 41
8. Irugbin ori ilẹ rere -- awọn ti o fi ọkàn ti o tọ́ gbà á, Matteu 13:8, 23; Luku 8:15

**III Ikilọ fun Awọn ti kò Mu Ọrọ Naa Ṣe**

9. Ibeere awọn ọmọ-ẹyin: "Ẽṣe ti iwọ fi nfi owe ba wọn sọ̀rọ?" Matteu 13:10
10. Owe wà fun awon ti ko mọ ohun ijinlẹ ti Ijọba Ọlọrun, Matteu 13:11
11. "Ẹnikẹni ti ko ba si ni, lọwọ rẹ̀ li a o si gbà eyi ti o ni" Matteu 13:12; Luku 8:18
12. Ifọju ati eti didi ti ẹmi awọn ti ko riran ti wọn ko si gbọran, Matteu 13:13; Johannu 1:9; 3:19

**IV Asọtẹlẹ Isaiah Tun Ṣẹ**

13. Ọrọ Oluwa si Israẹli ni igba nì: ni riri wọn kò ri, ni gbigbọ wọn kò gbọ, Matteu 13:14; Isaiah 6:9
14. Wọn yadi wọn si fọju, ki wọn má ba gbọ ati ki wọn má ba riran, ati ki a ma ba gba wọn là, Matteu 13:15; Isaiah 6:10
15. Ibukun ni fun awọn ti o ri, ti o si gbọ awọn ohun wọnni ti awọn wolii n fẹ lati ri, Matteu 13:16, 17; 1 Peteru 1:10-12

## ALAYE

**Awọn Owe Jesu**

Ọpọlọpọ awọn ẹkọ Jesu ni a fi owe gbe kalẹ fun itọni gẹgẹ bi a ti sọ ọ tẹlẹ nigba laelae, pe "Gbogbo nkan wọnyi ni Jesu fi powe fun awọn ijọ enia; kò si ba wọn sọ̀rọ bikoṣe li owe: ki eyiti a ti ẹnu woli sọ ki o ba le ṣẹ, wipe, Emi ó yà ẹnu mi li owe; emi ó sọ nkan wọnni jade ti o fi ti ara pamọ́ lati iṣẹ̀dalẹ aiye wá" (Matteu 13:34, 35; Orin Dafidi 78:2). Jesu, Olukọni ti o ga ju lọ ṣe eyi fun ire gbogbo ẹda eniyan. A ṣe alaye owe gẹgẹ bi "fifi nnkan wé nnkan." Awọn owe Jesu jẹ afiwe laaarin ohun ti aye yii ti a mọ̀ daradara ati awọn ohun ti ẹmi ti a ko mọ pupọ nipa rẹ̀, ki awọn eniyan ba le ni oye ti o jinlẹ si i nipa awọn ohun wọnni "ti Ọlọrun ti pèse silẹ fun awọn ti o fẹ ẹ." Iwe Mimọ́ si kọ́ ni pe ifiwera ti o ga wa laaarin ohun ti aye yii ati ohun ti ẹmi. Nitori naa owe Jesu wọnyii ki i ṣe àlọ́; o wà lati fi otitọ hàn, ki i ṣe lati fi otitọ pamọ. Iṣẹ eṣu ni lati bo otitọ mọlẹ, ṣugbọn Jesu wá lati fi otitọ hàn, ohun ti o jọ ni loju pupọ nipa awọn owe Rẹ̀ ni pe wọn ko ṣoro lati yé ni. Oun ki i lo ede awọn onimọ ẹ̀kọ́ Ọrọ Ọlọrun. Ọna bayii ni Olukọni nla yii n gbà lati fi gbe otitọ kalẹ ki o ba le ye awọn eniyan gẹgẹ bi oye wọn ti mọ. "Ọpọ ijọ enia si fi ayọ̀ gbọ́ ọ̀rọ rẹ̀."

**Ifọju ti Ẹmi**

Ṣugbọn a tun le gba ọna miiran kiyesi ọran mimoye awọn ohun ti ẹmi yii. Nigba ti awọn ọmọ-ẹyin beere idi rẹ̀ ti Jesu ṣe n fi owe ba awọn eniyan sọrọ, O dahun pe, "Ẹnyin li a fifun lati mọ̀ ohun ijinlẹ ijọba ọrun, ṣugbọn awọn li a kò fifun" (Matteu 13:11). Jesu si tẹsiwaju ninu alaye pe awọn eniyan kan wa ti eti wọn wuwo nipa ti gbigbọ́ lati moye ohun ti ẹmi. Iru awọn eniyan bayii wa ni akoko Isaiah; wọn wa ni akoko ti Jesu; wọn si tun wa ni akoko ti wa yii pẹlu. Nitori eyi ni Oluwa ṣe n kilọ nigba gbogbo bayii "Ẹniti o ba li etí ki o gbọ́." O ṣe e ṣe ki eniyan jẹ ẹni ti ọpọlọ ori rẹ pe ṣanṣan, ṣugbọn ki o jẹ ẹni ti o ya ope patapata nipa ohun ti ẹmi. Awọn akọwe, ati awọn Farisi ti akoko Jesu jẹ apẹẹrẹ iru awọn eniyan bayii. Jesu n fẹ lati gbin otitọ sinu ọkan awọn eniyan, lai si eyi ti ko le ṣe e ṣe fun ẹnikẹni lati ni oye ohun ti ẹmi. "Enia nipa ti ara kò gbà ohun ti Ẹmí Ọlọrun wọnni: nitoripe wère ni nwọn jasi fun u: on kò si le mọ̀ wọn, nitori nipa ti Ẹmí li a fi nwadi wọn" (1 Kọrinti 2:14). "Bi ihinrere wa ba si farasin, o farasin fun awọn ti o nù: ninu awọn ẹniti ọlọrun aiye yi ti sọ ọkàn awọn ti kò gbagbọ́ di afọju, ki imọlẹ ihinrere

Kristi ti o logo, ẹniti iṣe aworan Ọlọrun, ki o máṣe mọlẹ ninu wọn" (2 Kọrinti 4:3, 4). Ko yẹ ki o ya wa lẹnu nigba naa pe ọpọlọpọ ni o ni oju fun ririran, ṣugbọn wọn ko riran; ti wọn ni eti lati gbọ, ṣugbọn wọn ko gbọran. Ninu ọkan ni iṣoro yii wa, ki i ṣe ninu ero.

**Owe Afunrugbin**

Afunrugbin ti inu owe yii ni Jesu Kristi Oluwa. "Ọmọ-enia li ẹniti nfunrugbin rere" (Matteu 13:37). "Eso rere nì" ni Ọrọ Ọlọrun (Luku 8:11), eyi ti Jesu n funrugbin rẹ̀ lakoko yii bi O ti joko sinu ọkọ ti O si n kọ ọpọ eniyan ti o duro niwaju Rẹ̀. Ilẹ ti Irugbin yii bọ si ni awọn eniyan ti n gbọ ọrọ Rẹ̀. Nitori naa awọn olugbọ wọnyii ni apẹẹrẹ owe naa gan an niwaju wọn, eyi ti Jesu n kọ́ wọn. Ṣugbọn itumọ owe yii ki i ṣe ti awọn ti o duro niwaju Rẹ̀ nikan. Owe yii jẹ asọtẹlẹ pẹlu nitori pe o n fi han gbangba iru ọkàn ti awọn eniyan yoo fi gba Ọrọ Rẹ̀ bi a ti n waasu "Ihinrere Ijọba yi."

Jesu ni Olukọni ti o ga ju lọ ti aye ti i mọ̀. Mose olufunni ni ofin sọtẹlẹ nipa Rẹ̀ bayii, "OLUWA Ọlọrun rẹ yio gbé Woli kan dide fun ọ lãrin rẹ, ninu awọn arakunrin rẹ, bi emi; on ni ki ẹnyin ki o fetisi" (Deuteronomi 18:15). Nigba ti Jesu si wa lori Oke Ipalarada, Ohun kan lati Ọrun wa wi pe, "eyiyi li ayanfẹ Ọmọ mi, ẹniti inu mi dùn si gidigidi; ẹ mã gbọ́ tirẹ̀" (Matteu 17:5). Gbogbo awọn olukọni iyoku "ti inu erupẹ̀, ẹni erupẹ̀"; ṣugbọn lati oke ni Jesu Oluwa wa ti wá, otitọ yii si ni Nikodemu jẹwọ nigba ti o wi pe, "Awa mọ̀ pe olukọni lati ọdọ Ọlọrun wá ni iwọ iṣe." "Ẹniti o ti oke wá ju gbogbo enia lọ: ẹniti o ti aiye wá ti aiye ni, a si ma sọ̀ ohun ti aiye: ẹniti o ti ọrun wá ju gbogbo enia lọ" (Johannu 3:31). Bi o ba jẹ pe a n fẹ lati fi Ọrun ṣe ile wa, a ni lati fara balẹ gbọran si awọn ẹkọ Olukọni nla yii.

Ọrọ ti Jesu mu wá lati oke ni pẹlu. "ọ̀rọ ti ẹnyin ngbọ́ ki si iṣe ti emi, ṣugbọn ti Baba ti o rán mi" (Johannu 14:24). O si tun sọ nipa Ọrọ yii pe, "ọ̀rọ wọnni ti mo sọ fun nyin, ẹmi ni, ìye si ni" (Johannu 6:63). Iyanu ni aṣiri iye ti o wa ninu Ọrọ Ọlọrun. Jesu wi pe, "Ọrun on aiye yio rekọja, ṣugbọn ọ̀rọ mi kì yio rekọja" (Matteu 24:35). Bayii ni akọsilẹ Peteru wi nipa "ọrọ" wọnyii, "Bi a ti tun nyin bi, kì iṣe lati inu irú ti idibajẹ wá, bikoṣe eyiti ki idibajẹ, nipa ọ̀rọ Ọlọrun ti mbẹ lãye ti o si duro" (1 Peteru 1:23).

Nitori naa ko si abuku ninu Afunrugbin, tabi Irugbin. Lati Ọrun ni awọn mejeeji ti wa. Abuku ti Jesu n tọka si ninu owe yii wa lara ilẹ, eyi ti i ṣe "ti inu erupẹ̀." A ti gbin Irugbin naa ni otitọ, yoo si mu iye wà nibikibi ti o ba ti ri ilẹ rere. Nitori naa Jesu tẹsiwaju lati ṣe apejuwe ilẹ naa ti a gbin Irugbin naa si.

**Awọn ti Ẹba Ọna**

Iru ilẹ ti a kọkọ ṣe apejuwe rẹ ni ti "ẹba-ọna" ti atẹlẹsẹ awọn ero ti sọ di lile. Irugbin wọnni bọ sori rẹ; ṣugbọn awọn ẹyẹ wa, wọn si ṣa a jẹ: "Nigbati ẹnikan ba gbọ́ ọ̀rọ Ijọba, ti kò ba si yé e, nigbana li ẹni-buburu ni wá, a si mu eyi ti a fún si àiya rẹ kuro." A le pe awọn wọnyii ni olugbọ alaibikita. Wọn gbọ Ọrọ naa, wọn si ba ọna ti wọn lọ, wọn si gbagbe ohun ti wọn gbọ. Awọn ohun ti aye jọ wọn loju ju awọn ohun ti ẹmi lọ. Lọjọ oni ogunlọgọ eniyan ni **aibikita** n mu ki o padanu Ijọba Ọlọrun.

**Awọn ti Ilẹ Apata**

Ilẹ keji ni ilẹ "apata." Eyi ni ilẹ ti irugbin bọ si, ṣugbọn nitori pe ko ni gbongbo ti o jinlẹ, nigba ti oorun goke o si jona, afẹfẹ si gba a lọ. Jesu ṣe alaye pe, "Ẹniti o si gbà irugbin lori apata, on li o gbọ́ ọ̀rọ nã, ti o si fi ayọ̀ gbà a kánkan; ṣugbọn ko ni gbongbo ninu ara rẹ, o si pẹ̀ diẹ li akokò kan; nigbati wahala tabi inunibini si dide nitori ọ̀rọ na, lojukan na a kọsẹ̀." A le pe awọn wọnyi ni **olugbọ alaiṣorootẹ.** Alaiṣorootẹ eniyan ni ẹni ti o gbọ Ọ̀rọ naa ti o si gba a sinu ọkan rẹ, ti o si fi **ayọ bẹrẹ igbesi aye** Onigbagbọ. Ṣugbọn o kuna lati ṣiro ohun ti yoo gba a, ko si ṣe tan lati doju kọ ipọnju ati inunibini ti yoo dide lai pẹ jọjọ si olukuluku ẹni ti o bẹ̀rẹ̀ lati ja Ogun Igbagbọ́. Jesu ko fi wa silẹ ninu okunkun nipa otitọ wọnyii: O gba olukuluku ẹni ti yoo jẹ ọmọ-ẹyin Rẹ̀ ni imọran lati kọkọ ṣiro ohun ti yoo gba a (Luku 14:25-33). Ọgọọrọ eniyan ni o n kuna lode oni lati rin ọna naa ja nitori pe wọn ko ṣiro ohun ti yoo gba wọn.

**Awọn ti Ilẹ Ẹ̀gún**

Oluwa wa tun jẹ ki a mọ ninu owe yii nipa awọn ẹgbẹ kẹta ti wọn kuna lati de opin ire-ije wọn. "Diẹ si bọ́ sarin ẹ̀gún; nigbati ẹ̀gún si dàgba soke, o fun wọn pa." O si ṣe alaye pe, "Awọn wọnyi li awọn ti a fun sarin ẹgún; awọn ti o gbọ́ ọ̀rọ na, aniyan aiye, ati itanjẹ ọrọ̀, ati ifẹkufẹ ohun miran si bọ sinu wọn, nwọn fún ọ̀rọ na pa, bẽli o si jẹ alaileso" (Marku 4:18, 19). A le pe awọn wọnyii ni awọn **olugbọ to kun fun aniyan ṣiṣe**. Marta jẹ ẹni kan ti o tẹ̀ si iha bẹẹ. O pe Oluwa rẹ lati wa si ile rẹ, ṣugbọn aniyan ohun pupọ lati fi ṣe alejo ni o kun ọkan rẹ, nigba ti arabinrin rẹ Maria joko lẹsẹ Jesu ti o si n gbọ Ọrọ Rẹ̀. Inu bi Marta o si wi pe, "Oluwa, iwọ kò kuku ṣu si i ti arabirin mi fi mi silẹ lati mã nikan ṣe aisimi?" Jesu si da a lohun pe, "Marta, Marta, iwọ nṣe aniyan ati lãlã nitori ohun pipọ: ṣugbọn ohun kan li a ko le ṣe alaini. Maria si ti yàn ipa rere na, ti a kò le gbà lọwọ rẹ̀" (Luku 10:38-42). Bi ọmọ-ẹyin Jesu Kristi Oluwa ba gba "aniyan aye yi" laaye lati gba ọkan rẹ kan to bẹẹ ti o fi gba "ipa rere" naa lọwọ rẹ, iṣisẹ diẹ ni o ku ki "itanjẹ ọrọ̀, ati ifẹkufẹ ohun miran si bọ sinu wọn" ki o si "fún ọ̀rọ na pa." Ọpọlọpọ si ni awọn olootọ ọmọ-ẹyin Oluwa ti o ti pari irin-ajo wọn bẹẹ.

Nihin ni a ri awọn eniyan orişi mẹta ti ki yoo le wọle Ijọba Ọrun, ni ọjọ nla nì nigba ti ipe yoo dun – ki i şe nitori pe wọn jẹ ope nipa Ọna naa, şugbọn nitori pe nigba ti wọn gbọ Ọrọ naa wọn kuna lati pa a mọ sinu ọkan wọn. Irugbin naa ko si so asogbo. Şugbọn eyi ti o wu ni lori ninu owe yii ni pe awon ẹgbẹ kan wa ninu eyi ti eso naa "bọ si ilẹ rere, o si so eso, omiran ọgọrọrun, omiran ọgọtọta, omiran ọgbọgbọn." "Ti ilẹ rere li awọn, ti nwọn fi ọkàn otitọ ati rere gbọ ọrọ na, nwọn di i mu şinşin, nwọn si fi sũru so eso" (Luku 8:15). Awọn wọnyii ni a le pe ni awọn ti o fi **ọkan otitọ gbọ.** Jesu ti mu ki o ye ni kedere ninu owe yii ati ninu ọpọlọpọ ẹsẹ ninu Iwe Mimọ́ pe ki i şe gbogbo awọn ti o bẹrẹ ire-ijé Igbagbọ́ ni yoo pari rẹ si opin rere. Ko si şoro lati mọ eyi ti a wà ninu awọn ẹgbẹ mẹrẹẹrin yii.

**"O san fun mi ki n ba Jesu nikan rin,**
**Ki okuta si jẹ irọri mi bi ti Jakọbu,**
**Ki n ma wo oju Rẹ̀ nigba gbogbo,**
**Ju pe ki n ya lọ kuro nipa ọna mi**
**Ki n si kuna lati de opin."**

### AWỌN IBEERE

1. Ki ni idi rẹ ti Jesu şe n fi owe waasu Otitọ?
2. Ki ni şe ti O n fi owe ba awọn eniyan sọrọ, şugbọn ti O n sọrọ lọna ti o ye ni kedere fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀?
3. Ki ni şe ti oye Otitọ maa n ye ẹni ti a tunbi ju ẹlẹşẹ lọ?
4. Ki ni irugbin naa ti Jesu fún, ọna wo ni O si gba funrugbin naa?
5. Orişi ilẹ meloo ni o wà, apẹẹrẹ ki ni wọn si duro fun?
6. Ki ni şe ti Jesu tẹnu mọ ọn pe O şe pataki lati gbọ ọ̀rọ Oun?
7. Sọ ọrọ ti Jesu maa n sọ lati igba de igba, ni akoko işẹ-iranşẹ Rẹ̀ lati fi idi rẹ mulẹ pe gbigbọ ọrọ Rẹ̀ şe pataki.
8. Ni ọna wo ni ọrọ Rẹ̀ fi dabi irugbin?
9. Sọ igba kan ninu Bibeli ti o fi agbara ọ̀rọ Rẹ̀ hàn?
10. Ki ni yoo şẹlẹ si ẹni ti o kọ ọrọ Rẹ̀, tabi ti ko bikita lati gbọ ọrọ Rẹ̀?